To The Chief Secretary to the Gover
Lagos

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. V. No. 260 SATURDAY, FEBRUARY 4, 1928 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

15 FEB. 1928



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

*[A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.]*

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

*[Fun Atọsi lailai ati titun.]*

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, l o si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.

"AWA O MA JO, AWA O MA YỌ, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akękęyęyę pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ęgbę, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

Office :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos; also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

# Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKĘ Onişowo Gbabiogędę nta Panu-kikọle ati kikanko, Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilękun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ti Ọgan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idumagbo Street, (l'ebute Ọkowa) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işę Agbędę Iworo ati Fadaka.

**Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibę.**

---

**Are you a Mechanic ?—**If so you must want Tools, now or soon!

**Do you intend to put up a house ?—** Then you will require Builder's Hardware.

In either case you cannot do better than call at

## B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

## J. C. VAUGHAN

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-oyọku.

Ilękun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silę fun awọn Ọmọle ati awọn Gbęnagbęna : bi o fę awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ o ni'ya lati ri nibę :

Alagbędę Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gbogbo l'oşe fun ọ lati re yan irin-işę tirę nibę ba kanna.

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Ajanaku lọjọ to ti pę : bi Ọgędę si ni Owo rę ngba kakiri ibikibi. Agbę ni ọ kai ! bi o ri orişirişi ọja ti o ri ra nibę ha yio şe o.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbęnagbęna, iwọ Aranbata, iwọ Asẹnję iwọ Ageginigbo (*Sawyer*), Alagbędę Wura, iwọ Alagbędę Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirę pade nibę.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremerejibe.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/ | 13/- | 14/ |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ ti owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

AT' AREDE, AT' AREDE,
KA GBỌ TI JESU RE MO MỌ.

Irufẹ orin Arofọ Ṣobọ Arobiodun Apa-'kuta ran'wa elehin erin yi ni o wasi iranti wa nigbati a rĩ ẹda apakan iwe ti a sọ pe Alufa O. J. Griffin, Olori awọn Ijọ Wẹsilẹmu ni ilẹ yi kọ fun ffọwọsi ikọkan ninu awọn *member* rẹ lati fihan pe olukuluku wọn ko ni ju aya kan lọ, eyiti nwọn ba ti gbe ni Arede lọna Ijọ ati ilana Ṣọṣi Wẹsilẹmu ti iṣe ọmọ lẹhin Kristi. A gbọ pe iwe yi ṣi ufi dugbẹdugbẹ, a si ṣe iranti pe irufẹ ọrọ bayi lo mu Ijọ Ṣọṣi Weslemu ti Ereko da si meji ni ọdun jọjọ sẹhin tobẹ ti pupọ fi ya, ti nwọn si da Ṣọṣi "Ẹlẹja" silẹ. eyiti o ngbilẹ nisisiyi ; ti a ba ma rõ jinlẹ. ẹlomiran le ṣe irufẹ ibere ijinlẹ yi "Kristi papa ti gbogbo Ṣọṣi ntẹle ha gbeyawo bi" ?

Gẹgẹbi a si ti ri ka pe Olori Ijọ awọn Wẹlslẹmu na npete nisisiyi lati fi iṣẹ silẹ lọ gba isinmi, a ro pe ki yio da rukerudo silẹ ni Ṣọṣi rẹ ki o to lọ nipasẹ ọrọ iwe afọwọsi yi ati pe ki yio si jẹ ki owe yi ṣẹ si on lara "Bi Oyinbo ba fẹ lọ a ṣu s'aga."

ỌLỌJA, Ẹ MA KU ỌJA.

A gbọ pe ko si bo ti ri ni ọja ti Alabojuto Ilu pẹlu awọn saraki-saraki lọ ṣi ni Yaba ni *Saturday* ọsẹ to kọja ; Ijọba si ṣe omi itọ (*Creek*) bi ti "odo Jordan" ni ọna Ikoyi fun awọn ero ọja ti nwọn yio ma mu ọja wọn wa lati Ọjọ, Ejinrin tabi ọja okere miran.

ABIYAMỌ KU 'RỌJU.

A ba Ọgbẹni Herbert Macaulay kẹdun ofọ ti o ṣẹ ni *Friday* to kọja nipasẹ Paula Aina wundia ọmọ rẹ kan ọlọdun mẹtalélogun ti o jalaisi ni ile rẹ, Kirsten Hall, Balbina Street, lọjọ na: bẹ si tun ni a ba kẹdun iku ọmọ-kọnrin ọmọ ologbe ẹgbọn rẹ, Alufa Hugh Macaulay ti Bonny ti o lọ jẹ ipe Olodumare ni Wesley Street ni ọjọ *Monday* ẹsẹ yi ; ki Baba O'utunu maṣai tũ ni'nu ati awọn ara gbogbo, Amin.

AIYE IJỌHUN KO JỌ TI ISIYI.

LATI ỌWỌ KEKERE- AWO.

Si Oniwe-irohin "Eko Akete,"

Mo bẹrẹ foji o,

Ni ọsẹ to kọja a sọ nipa ai fimọ ṣọkan to mbẹ larin awọn enia dudu wa ni ilẹ yi nipa ọran owo, gẹgẹbi awọn enia funfun ti so ọwọ pọ ti nwọn mu ara wọn ni ẹjẹ kanna, ti gbogbo ohun ti nwọn si nṣe si ngun rege fun wọn, eyiti o nmu awọn enia dudu ko bẹrẹ fun wọn lọjọ ti oni.

Ki a tilẹ ni awọn enia dudu wa ni irẹpọ ati ifọmọsọkan, eyi ko ni ki enia dudu ti itori pada jẹ baba tabi ẹgbọn fun enia funfun, nitoripe lati kekere Ajanaku li erin ti pọ ju ẹfọn lọ, lati ọjọ gbọrọ ni kekere enia funfun ti ju iran enia dudu lọ, boya a le ri ninu ẹlomiran ti o le sọ wipe nitoripe awọn enia dudu ko la ero pọ mọ arawọn ni ko tiṣe jẹki nwọn ju iran enia funfun lọ, bi ẹnikan sọ wipe on nlero iyẹn si ikun, o dabi wipe oluwarẹ ntan ararẹ jẹ ni.

Ohun ti a nfẹ ki o ye olukuluku wa daradara ni wipe kosi ẹtọ kan larin awọn enia dudu ti nwọn nṣe fun arawọn bikọṣe iwa arankan tabi iwa keta.

Ṣugbọn a fẹ ki olukuluku nyin mọ wipe o to aseko nisisiyi lati parada fun enia dudu lati wa ni irẹpọ, gẹgẹbi awọn iran enia funfun ; eyiti a nsọ yi ẹniti o ba si ni ewo lo kan on nibẹ ebi ko pa on orugbẹ ko gbẹ on kini wabala kilopo, irufẹ awọn enia bẹ ki iṣe ẹniti ero ori rẹ pe daradara ati pẹlu adagba jẹ Dani tabi amudodo ni suna ti o yẹ ki a fun oluwarẹ.

Bi ẹnikan tilẹ nsọ wipe ọran ti ko kan on arara li a nsọ yi, awa ko ro wipe irufẹ ẹnibẹ ni ero rere kan fun ilu rẹ, ẹniti ko si bikita rere kan fun ilu rẹ, ki a wo oluwarẹ daradara, enia buruku ti o ju oluwarẹ lọ kosi.

Li aseko ti a wa loni yi ọran iṣẹ tabi owo lo ndamu ọgọrọ enia, ẹlomiran ji loni ko ri ibi iṣẹ kan lọ, kosi okowo kan lọwọ rẹ, o nsun o nji o nnawo ṣa, ṣugbọn kosi ọna aye ti owo le ma gba wọ inu ile fun oluwarẹ, dajudaju oku enia li oluwarẹ wa, ki iṣe ẹniti o ku ti a gbe sinu Posi ti a lọ gbe sin nikan ni oku, bi a ko ba mọ ; eyiti a wi yi ni oku li ọna keji fun ẹda.

O ti jẹ balẹ-ile tabi iya-ile kan ri, Pọnun mẹwa ko wọn o ri lati na gẹgẹbi o ti fẹ, o tun di aseko kan, lati na Pọnun kan tun pada ṣarẹ oluwarẹ atamọ ṣile kan pẹlu, oku ni oluwarẹ tabi aye ? dajudaju oku ni oluwarẹ.

Ni ilẹ ti o mọ loni, o ni iye ọmọ enia ti o ji ti o mu ọna igboro ilu bi Ẹhingbẹti, ni Ṣọbu awọn oyinbo oniṣowo lati ṣiṣẹ Akọwe tabi lati ṣiṣẹ iranṣẹ ni Ọfisi tabi lati ṣiṣẹ gbe-rumi-sọmi (Shop boy) ni Ṣọbi tabi ti o fori le ọgba Locco ni Ebute Mẹtta tabi ni P. W. D. Ijọra tabi ni Apapa tabi ni Dry Dock ni Etikun lati ṣiṣẹ Afagi, mọle-mọle, Alurin, Atoje, tabi awọn iṣẹ bẹbẹ tabi lati ṣiṣẹ Akọwe Ṣọbu fun ọja tita (Shop Keeper) tabi (Sales man) ti o nlọ ti o mbọ ti ko ri aye wọnyi, ti nwọn nfi eni deni fọla dọla fun u sibẹsibẹ ti nwọn ko gba si ibi iṣẹ ti a ka wọnyi, aiye ijọhun ha jọ ti isiyi? O ti o! ko jọ ti isiyi.

Ni igba lailai ti iṣẹ mbẹ ti gbogbo nkan nlọ daradara, ti c jẹ wipe enia fẹrẹ le bu iyẹpẹ ilẹ lasan ki o si sọ di owo nina, bi o ba kọ iṣẹ gbẹna-gbẹna (Carpenter) tabi iṣẹ mọlemọle (Bricklayer) ebiko pa oluwarẹ mọ, nibo lo ma kọ iwe iṣẹ wiwa (Application) lọ ti nwọn ko ni gba ọ lẹsẹkanna ti nwọn a si ma san owo gere bi ṣile marun lojumọ fun oluwarẹ, eyi ha ri bẹ mọ lode ti oni ẹnyin arabi ?

Bi nwọn ba jaja gba ọ ni Apapa, tabi ni Ikoyi tabi ni Ijọra boya ṣile mẹta tabi ṣile meji abọ ojumọ li nwọn yio ma san fun oluwarẹ, afi ọga-iṣẹ papa li a ro wipe yio ma gba to ṣile mẹrin tabi mẹrin abọ nisisiyi.

Ki a tilẹ ni iṣẹ aṣọ riran li o kọ, ẹniti koi ti jẹun kanu li yio sọ wipe on nroju lati ran aṣọ, bi iba aṣọ ti oluwarẹ ni tilẹ ngbo lọ, bi o ba ti gba kọ li oluwarẹ yio fi ṣe e, di igba ti aṣiri yio fi bo, o mbẹ ninu ọpọlọpọ enia ti o jẹ wipe bi aṣọ rẹ ba ti lu fin, ọmọ ọdọ tabi alumọngiri lo ma gbe fun, ṣugbọn nisisiyi, ki o to ra omiran lati gbe fun Tailor yio ri wipe eyiti o nlo na gbo kanlẹ kẹrẹ kosi aye fifi aṣọ lẹ nibẹ mọ,

Awọn ẹniti o si nṣe iṣẹ Alagbẹdẹ fadaka tabi ti Golu, agbarakaka ni ẹlomiran fi nri yeri tabi Ẹgba ṣe debi ẹwọn tabi Golu-Bidi nisisiyi, ọpọlọpọ enia ni yio fẹ wipe ti o ba di ninu ọdun, bi on ko tilẹ si ninu ẹniti o tun nṣe oge mọ ti yio fẹ lati sọrọ rẹpẹtẹ bi oruka Golu, yeri Ẹgba, Ẹwọn tabi awọn nkan bẹbẹ si ọmọ rẹ lọrun, ṣugbọn oluwarẹ nronu bi ẹlẹna ko tiṣẹ ni takun sinu iṣasun fun on, ati bi on yio tiṣe ri elo kan ti ẹ yio mu lọ, fi wọn gari bi panu meji tabi mẹta kan lọjọ Ọbun Eko tabi lọjọ Ebute Ero labọ ọja Ejinrin, ni Alagbẹdẹ kan ma ni on nri iṣẹ ṣe, ẹniti o si nṣiṣẹ ninu Ṣọbu ti o da Ṣọbu haya fun ararẹ, ọga ta ọja o ta owo alaru a pe, ni ti ẹniti o fi Ṣọbu haya fun wọn, bi ẹnifi o haya Ṣọbu ba si dogun ohun ti o jẹ gbese owo oṣu mẹta tabi mẹrin si ọrun, ẹniti o ni Ṣọbu yio fẹ lati le oluwarẹ kuro tabi ki o fọn ọn lẹjọ si Kotu.

Ọpọlọpọ ẹlomiran ti o kọ iṣẹ orişirişi ti o si mọ iṣẹ yi ti o fẹrẹ le yi lori, ṣugbọn o ha ri iṣẹ na ṣe bi ?

O wun ọpọlọpọ ẹlomiran lati ri wipe on da ile kan kọ fun ara on tabi fun awọn ọmọ on lẹhin ti on ba lọ, a ko sọ ti awọn ẹlomiran ti nwọn ngbe ile ọkọ ero, eyiyi ni Familie's House ti nwọn nṣe bi mojuwọnlọ lọpọlọpọ ani awọn ẹniti o nfẹ gbiyanju lati ri wipe ile lagbaja ni eyi, ile na ma dara o, oh, lagbaja yi kọle yi o kọ o, ṣugbọn ti koi tile mu irufẹ iyanju bayi ṣe, ki iṣe wipe eyi ko wu ọpọlọpọ enia, ṣugbọn idamu owo ha le jẹki eyi le ṣe, nibiti a gbe nkọ ile ni Birikila ati Kapinta debi alaru papa fi nri onjẹ jẹ, nigbati a ko kọ ile ti a ko kasẹ, kini awọn ẹniti a ka wọnyi yio jẹ bẹ atẹgun koṣe lanu si i.

Awọn ẹniti ko ri iṣẹ ṣe omiran nwa ki o ni ẹnikan ti yio gbe on ju sinu oko rẹ kan lati ma tọju rẹ fun u, ọpọlọpọ li o nfẹ lati ri wipe on ra oko kan lati ma jẹ anfani ohun Ọgbin bi obi Cocoa, Ọpẹ, Orogbo, Ata, Alubọsa, Gbaguda, Tumati, tabi awọn ohun ọgbin bẹbẹ ninu rẹ, nipa eyi awọn ẹniti o nwa iṣẹ alagbaro tabi alabojuto oko yio ma ri onjẹ ti nwọn jẹ ebi ko ni pa wọn, ẹniti ko ra oko ha le gbe oju gbaiya ki o lọ pe Wonlẹ-wọnlẹ pe ki o wa lọ ṣe Plan ilẹ tabi oko kan fun on, o daju pe, bi ẹnikan ba danwo, ti onikan ba gbe si Kotu, nwọn a ba ṣe ẹjọ ẹsẹ rẹ yio fẹrẹ tan nilẹ, bi nwọn ko ba tilẹ ba oluwarẹ ro ẹjọ ole diẹ loku, ati pẹlu bi enia ṣe bẹ fun ẹnikan ẹjọ ole ni nwọn yio ba oluwarẹ ro, nitoripe nwọn a ṣa bere owo ẹniti o gbe ti ra ilẹ, ati lọwọ onigbajo ti o ti ra a, lẹhina ki o to wa kan iwe ti onigbanjo ṣe fun nigbati o ra ilẹ.

Ogunlọgọ enia ti o si jẹ ẹniti o mọ owo Trade ṣe faufau, o gbọdọ ṣan ọwọ ofifo lọ si ọdọ awọn oyinbo niṣowo Lẹhingbẹti wipe pẹpẹsẹ on nfẹ lati ma ṣe owo fun wọn, ibere ti nwọn kọkọ ma bi i ni pe. kini yio fi duro, bi o ba ni on ko ni ohun ti on yio fi duro ṣowo nwọn a bi lere pe kini ero rẹ, tabi oluwarẹ ba ni ero on ni wipe ki

nwọn ma ko ọja fun on, ki on ma lọ ta ki on ma wa sanwo fun wọn, nwọn a ni "*Off you go*" bi oluwarẹ ba si npa su-su-su lọwọ tabi ti o nṣe dẹidẹi kan, nwọn a fẹrẹ le gba ni bata si ode, awọn eyiti o ba jẹ alanu diẹ tabi ti ara ko kan tobẹ ti o le sọ wipe bi oluwarẹ ko ba ni ohun ti yio fi duro ki o lọ wa enia wa ti yio fi ọwọ sinu iwe duro fun un, yio si ni adehun ninu nipa iye ọja ti nwọn yio ma fun ati bi o tiṣe ni lati ma wa sanwo ọja ti oluwarẹ ba ngba si i nipa eyi li oluwarẹ fi le ri owo ṣe, ṣugbọn kosi eyiyi nibẹ, oluwarẹ yio wọ Ẹhingbẹti pẹ.

Ọpọlọpọ ara ilẹ yi ti nwọn kọ iwe tabi ti ko mọ iwe li o nfẹ lati gbe iwe-ile rẹ lọ fi duro lati ma ṣe iṣẹ Ṣọbu fun awọn oyinbo ki o si gba Akọwe pẹlu ararẹ, ti Ọlọrun ba ni ki o ṣe ori're ni nwọn yio fi gba oluwarẹ aseko yi yatọ si aseko lailai, ki iṣe wipe nitoripe oluwarẹ ti ni ohun ti yio fi dogo si ọdọ oyinbo lati ma ṣiṣẹ, nitorina ki yio si wahala tabi ifoiya kan fun oluwarẹ mọ agbẹdọ aseko lailai ni iyẹn aiye ijọhun ko jọ ti isiyi. Ni igba lailai ti ọja dara fun toyinbo tenia Dudu ti gbogbo nkan ko di bi o ti da ti o jẹ wipe awọn onisọbu li o tun nlu agogo ẹnu pe awọn ero lati ra ọja ninu Ṣọbu awọn oyinbo onișowo ni nwọn ma nwa ẹniti nwọn yio fi sinu Ṣọbu lati ma ta ọja fun wọn, ti nwọn yio si ma san owo geregere fun wọn.

Awọn alejo oyinbo onișowo ti o tun wa ni aseko yi kosi nihin ngbana, ani oyinbo Lever kio ti ra ọpọlọpọ ile-owo awọn oyinbo Onișowo eyiti gbogbo wọn fẹrẹ di (*Combined Firm*) tan loni, kẹrẹkẹrẹ nipa iwa jamba ti nwọn nṣe fun awọn oyinbo, o di ogun ohun ti nwọn jagbọn wipe ti nwọn ba fẹ gba oluwarẹ si iṣẹ Ṣọbu, ki nwọn sọ wipe ki oluwarẹ lọ wa oniduro wa, ti oluwarẹ ba si ri oniduro mu lọ ti nwọn duro fun u tan nipa ki kọwọ bọ iwe, ti nwọn si ṣi Ṣọbu fun u, ti o si jẹ wipe ko lojọ ko loṣu, nwọn ka ọja Ṣọbu, o din rẹpẹtẹ, ẹniti o duro fun oluwarẹ kilo tijẹ ki o to din, o ta ọja win si ode, ti o di womi-nwolẹ, ti ko ri idahun, nipa eyi nwọn da gbọse si ọpọlọpọ enia lọrun eyiti o jẹ wipe o mbẹ ninu ẹlomiran loni ti o nrọ iru owo gbese bayi san ani owo ohun ti ko jẹ ti o nri ni gbọnsẹ, Nigbati awọn enia nri iru ifẹ iwa bayi, nwọn nsa nwọn nkandi lati ma ṣe iranlọwọ koda ọmọ iya wọn papa nipa ṣiṣe bẹ ko jẹki nwọn le ṣe ore fun arawọn mọ, awọn oyinbo tikalarawọn papa ti jagbọn wọn.

Bi ẹnikan ba lọ ba wọn nisisiyi wipe on nfẹ ki nwọn ṣi Ṣọbu fun on lati ma ta ọja, nwọn a bi lere wipe kilo fẹ fi duro ti o ba ni iwe-ile tabi Aganrandi ni, nwọn a bi lere wipe o fẹ fi duro fun ararẹ ni tabi nwọn fẹ fi duro fun u ni, ti o ba jẹ wipe oluwarẹ ni on nfẹ fi duro fun ara on ni, nwọn a ni tani ẹniti o ni ile, bi oluwarẹ ba sọ wipe on jogun rẹ tabi on ra ile na fun ara on, nwọn a ni ki o lọ ṣe Conveyance lọdọ Lọya, ki o si ṣe Plan pẹlu, lẹhinna nwọn a fẹ lati ran Lọya ti nwọn ba ni lọ wo ile tabi ohun ti oluwarẹ fẹ fi duro, ti o ba to iye ti nwọn nfẹ, ni nwọn yio to gba oluwarẹ, ṣugbọn awọn oyinbo omiran ko ma bikita iye ti ile kan tò tabi ti ko to, bi o ba wu wọn, nwọn le gba gẹgẹbi oluwarẹ ba ti fẹ, bi o ba si wu wọn nwọn le kọ, nwọn le sọ wipe, bi oluwarẹ ko ba ni ohun ti o le fi kun u, o le lọ wa enia ti yio ba fi ọwọ si iwe fun un.

Ti o ba si jẹ wipe nwọn nfẹ duro fun oluwarẹ ni, ti o ba jẹ ẹnikan ti o fẹ duro fun oluwarẹ yi kọ lo ni ile na, nigbati nwọn ba wadi rẹ lẹnu wọn, nwọn a sọ wipe ki nwọn lọ pe awọn iyoku ti nwọn jumọ ni nkan ti nwọn fẹ fi duro wa, bi o ba jẹ wipe awọn enia marun tabi mẹfa lo ni bi ọkan ṣoṣo ninu wọn ba sọ wipe ko tẹ on lọrun ẹran buṣe, nwọn ki yio gba oluwarẹ wipe e nitoripe ẹnikan ṣoṣo ni ko tẹ, aiyafi ti nwọn ba pin lo ya ku, 4ai si eyi nibẹ koṣeṣe! o di igba ti ẹnu gbogbo wọn ba ṣọkan ni iwaju oyinbo, ti o ba si jẹ wipe nwọn ṣẹ nri wipe ohun ti yio jẹ ṣegẹgẹ ni, nwọn le sọ wipe awọn ko gba mọ ọran pari.

Lẹhinna ẹwẹ ki a tilẹ ni oluwarẹ papa lo ni ile yi fuu ararẹ, tabi ti awọn ẹbi ni, ki ẹnu gbogbo wọn si ṣọkan lati ile lọ lati duro fun oluwarẹ ṣiṣẹ, bi oluwarẹ ba jẹ ẹniti ko mọ iwe nisisiyi nwọn ko ni fẹ gba mọ, bẹ ohun ti ọpọlọpọ wọn nwo ni wipe ẹniti ko mọ iwe ti o fẹ ṣiṣẹ lati responsible fun ararẹ, ti yio si ni akọwe ti yio ma ba ṣe iṣẹ rẹ, bi o ba di wipe ọja din ni Ṣọbu, ero wọn ni wipe oluwarẹ le sọ ti o ba dogun ẹjọ wipe on ko mọ iwe, ki o si pada jare, afi ẹniti o ti mbẹ labẹ wọn ri ti nwọn si ri wipe iṣẹ rẹ nlọ daradara, bi bẹkọ nwọn le sọ wipe ki oluwarẹ lọ wa ẹniti o mọ iwe wa, ki ẹniti o fẹ ṣ'ṣẹ papa jẹ Alabojuto ni Ṣọbu ti nwọn fi le gba lai si eyiyi nibẹ, ṣaṣa wọn lo nkọ lati ṣe gẹgẹbi a ti wi yi, kilo mu gbogbo iwọnyi wa? Kosi ohun meji nibẹ ju iwa jamba ti awọn oyinbo wọnyi nsa fun lọ.

Ni sa lailai awọn oyinbo onișowo ko mọ gbogbo ohun ti a nsọ yi.

Ti o ba de ọdọ wọn, ti o ba sọ wipe o fẹ ki nwọn ṣi Ṣọbu fun ọ, nwọn a ni o dara, awọn yio fi si ero, bi awọn, ba ti ro si, awọn yio ranṣẹ pe o, ti nwọn ba si ro ti o gun tan, nwọn a ni ki o lọ wa ẹniti yio duro fun ọ, ẹniti o ba si ti wa ni abẹ wọn tẹlẹtẹlẹ ti nwọn fi inu tan daradara nwọn ko kọ lati gbe Ṣọbu le lọwọ, nwọn a kan bi ọ lere wipe oye wo ni oluwarẹ ni nipa ọja tita, tabi irufẹ ọja wo ni o mọ ta, nwọn ki yio bi ọ lere wipe nibo ni o ti nṣiṣẹ ri, ati pẹlu iwe-ẹri (Testimonial) ti oluwarẹ gba nibiti o ti ṣe iṣẹ ri, kosi gbogbo iregbe tabi wahala wọnyi nibẹ, nwọn a kan gba oluwarẹ nwọn a si ko ẹru le lọwọ ni, aiye igba na ha jọ ti isisiyi mọ ẹnyin arabi?

**Gbogbo ọna ti awọn oyinbo onișowo nmu nkan wọn gba nisisiyi, awọn enia lo kọ wọn.**

Nipa eyi ni ko jẹki ẹlomiran le ni afọri loni, ki a tilẹ sọ wipe o mọ iwe o si ni oye daradara lati ṣe akọnta, ko ku bi o ti ṣe ma fi ri iṣẹ ṣe, o tilẹ ri ohun idogo iṣẹ lọwọ ki nwọn gba o na, ki nwọn tilẹ to jaja gba lati şi Şọbu kan fun ọ, wahala ti iwọ papa yio ri, 'wọ a ri iya 'wọ a fẹrẹ pe ni baba koda oluwarẹ, ko ni gbagbe lailai, ẹnikan a ṣe pọnpọn wahala ki iṣẹ to bọ si lọwọ, ki o de inu iṣẹ na tan, ki o ma wa ṣe iṣẹ na ni raurau, bikoṣe olori buruku enia.

Ẹnyin ara tabi ọmọ-ilẹ yi, tabi ẹnyin ti ẹ nfẹ lati ma ba oyinbo ṣe iṣẹ pọ, a ko sọ ti awọn ẹniti o nwa iṣẹ Ofisi lati ṣe, a mọ wipe olukuluku a bi tirẹ lara, ani awọn ẹniti onfẹ lati gba iṣẹ-Şọbu, ẹ jọwọ ẹ ṣe ironupiwada nipa iwa jamba, irufẹ awọn iwa ti a ka wọnyi, ki iṣe ẹnikan ṣoṣo li yio ba, yio tun ba ẹlomiran pẹlu ti yio fẹ lati jẹ anfani irufẹ iṣẹ bẹ, ṣugbọn ti enia buruku ti ba enia rere jẹ, awọn oyinbo nwọn ko sa mọ oju enia buruku yatọ si enia rere nigbati ko ba ti 'si wipe ẹnikan gba nọmba enia rere si iwaju.

Ẹ maṣe jẹki ori buruku ba iran enia dudu, ki o iba le jẹ ohun anfani tabi ohun irọrun fun randiran nyin lati ri ọna onjẹ laseko ti ẹ ba nfẹ.

Nipa iwa jamba ti ẹ nṣe lọdọ awọn oyinbo onişowo, o mu ki ẹ ma wa inira lati ri iṣẹ lọdọ wọn li aseko ti ẹ ba nwa, ṣe gbogbo nyin li ẹ roju aiye lode nisisiyi tabi ẹ ko roju aiye lode?

Bi ẹ ba nfẹ şişe Şọbu lọdọ oyinbo, ẹ tọju awọn ohun ti nwọn ko si nyin lọrun daradara, ẹ maşe ṣe aşeju nipa şişe ohun ti apa ẹni ko ka, ni ero wipe, ki o to to aseko lati ka ọja aşiri yio bo, a mọ wipe Kọmişọni ati owo-oşu mbẹ nitotọ, şugbọn iso kekere ba di ijẹ.

Lẹnu igba ti ọdun titun ti bẹrẹ, a şe akiyesi ọpọlọpọ ile ti awọn onigbanjo nta, ninu gbogbo ile wọnyi ti eyiti o fara kọ si ọdọ awọn oyinbo onişowo lo pọ, ju, nitorina li a tişe nke fun nyin,

Wahala ti a şe nipa anfani fifi oye gbogbo nkan lọna ti owo han ninu wosika wa ti ọsẹ yi, aişe fun itori rere ilu yi ati nitori ọran ẹhin ọla, ẹniti a ba wifun ki o gbọ ki o gba.

"Bi ojo o rọ
Bi igbado o gbo
Oju gbogbo nyin ni yio ja a."

Emi ni tiyin nitotọ,
KEKERE AWO.

## KINI A NPE NI IGBA (TIDE.)

[ LATI ỌWỌ ỌMỌ AWO ]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

O jẹ ohun ẹdun mi fun ọpọlọpọ ọdun lati la ohun ti a npe ni Igba ye awọn ẹlẹgbẹ mi, omiran ti nwọn fẹ le şe ara wọn leşe nigbati igba ba yi pada fun wọn.

Ẹ jẹ ki a bi ara wa, kini a npe ni igba, ẹlomiran nigbati o ba jẹ toyo tan, ti gbese kun ọrun rẹ, bi igbati ẹşẹ ko ba kun ọrun enia a wa bọ sita a ma jo kiri a ni on lo igba pataki awọn Imale, ẹlomiran kẹ a ni on nlo igba ti on nipa ki ko obinrin jọ, a ko wọn jọ janrẹrẹ bi igbati akukọ ko ba ko obi diẹ jọ sile ti a si nşe ọkọ gbogbo wọn, eyi owọ onjẹ ko ni fi silẹ to fun nile a ni pẹpẹşẹ on nlo igba. Omiran kẹ a ma lo igba tirẹ nipa kikọ ile lẹ fun obinrin ti on pe ni Alarede rẹ *(married woman)* ti o ti sọ di *(good for nothing woman)* alarede, a wa ma lo igba tirẹ nipa kiko obinrin miran jọ sita a wa ma fi ebi pa ti ile: ka da silẹ ka tun tun şa, şaşa ọdọmọkọnrin papaki ẹniti oju meji tabi mẹta mọ to ma le gbe pẹlu obinrin kan şoşo titi ọjọ aiye rẹ, ẹniti o ba nfi ọwọ sọ aya fun iru yẹn on tan ararẹ jẹ, ọbọ lagido enia lo si le gba iyẹn, o ti gọngọsu odidarẹ ko jẹ gba yẹn lọwọ enia kan. Bo tilẹ ta fun, nigbati ẹlomiran ba wa ohun to ma wi ti a ni mẹ l'Ọlọrun wi, nibo ni Oluwa gbe sọkalẹ wa sọ fun ẹ pe ko ma ko obinrin jọ, ko si ma fi ebi pa ti ile bẹni ninu igba niyẹn wa.

Ẹlomiran kẹ a ni on nlo igba nipa aşọ wiwọ, finifini ojojumọ. Omiran kẹ a ni on fẹ lo igba şugbọn ko si apekanuko lọwọ rẹ, mo bere melomelo la wọn gbajumọ gbajuta, ti nwọn ti farakọ sọdọ awọn Oyinbo kakiri nipa owo ati lo igba ẹ jẹ ka tun bi arawa, igba kan ha bẹ ninu eyi afi eyi ti Oluwa ma fun ni lati oke.

Ẹnikan oke ọhun, owo titi, o ni ki Oluwa ma fun on lọrọ pupọ, o ni ti on ba ti nri onjẹ ojọ on jẹ ọran tan.

Ẹlomiran ma gbagbe ohun kan lẹhin igbati Oluwa ba fi ẹbun owo diẹ fun wọn, wọn a gbagbe ara wọn patapata, bi enia ko tara kuro lọna fun wọn, wọn a fẹ le fi mọto tẹpa, wọn a ni ko ni jẹ ju owo lọ, nigbati o ba ya. Ọbanjigi tikalararẹ, ti o ba fẹ da iru ọrọ bawọnni pada si awọn onigberaga wọnyi nigbana ni, wọn a wa mọ Ọlọrun ni wa ma gbọ ti nwọn a ma wipe—Oluwa kinni mo ri yi opin de si ohun gbogbo şugbọn nkankan ni awọn enia wa ma ngbabge pe ọranyan ni ki igba yipada enia ko gbọdọ ma wa ninu ipo rẹ kanna lọ titi, ẹniti tirẹ ba ri bẹ ẹmi ko ni pẹ laiye, ti ẹ ba şe akiyesi daradara ẹ o ri pe ki ẹlomiran to di ẹniti o ni

dukiya lowo, ati jiya pupọ ti ko ni le fẹnu sọ tan, ẹ o si ri pe olowo miran, ti a fun nigba ewe rẹ ti ko fi mọ ẹlomiran, to nṣa ni inakuna, ti o fi nṣe gbajagbaja rederede, awọn le ma uri ti nwọn ma jẹ ika nitori bẹni ẹlomiran kẹ a ri imi ẹran bayi a fẹ le pe lowo. Ẹniti o nṣiṣẹ fun arare ri, a di ẹniti o npada nṣiṣẹ labẹ ẹniti on ti nṣe fari si, omiran ko tilẹ ni ri iṣẹ ṣe arara, gbogbo ohun dukiya rẹ ti o ti fi gbe ra, a wa di ifi inira ta fi jẹun, Oluwa ko ṣọni ninu rẹ—mo ranti Ọgbẹni kan, o si tun je gbajumọ, o ni aya kan ti a npe ni Arẹwa obinrin *( a daughter of sin )* ẹniti o jẹ pe a nwa ni ta to le mọ ni ti ẹnu kọ, o dara to obinrin. Dendere.

She is a perfect beauty, incomparable—Ọkọ papa ti a nwi yi ọ unrin mẹta ni ki ama da lọ popopo, nigbati o nlo igba ko si ẹniti o to, ko si rope igba ma yi rara, ani nigbati o wa ninu ọla rẹ ti o nṣe bi o ti wun ngbọ kini olowo kole ṣe, alagba kan, ti o ngbe ile rẹ ma nlo ede yi fun ni igba ku gba ti owo ba ngun lori tan g a, a ma dahun, asi ma sọ fun pe ni ede yi, eyi ni nipe lagba—gba a mọkọ ẹ o. A! ẹnikeji, ani nigbati o nye ọjọ, oṣu, ati ọdun, ti obinrin alagba yi ma nlo ede fun bayi, o wa dahun ni ọjọ kan nigbati iyawo rẹ wa lọdọ rẹ pe, ngbọ arẹwa, iyawo temi nikan, igba kan ha tun le kọ mi, ngo ma wo bi yio ti ṣe kọ mi, ngbọ loni nko, eyin ọkawe Eko Akete igba ti yi fun ẹni yi. Ayipada ti rẹ ko to ti awọn ẹlomiran ti o si ndamira laiṣobinrin, o si ma da yanvọn silẹ, o gbagbe pe Oluwa kanna ti o nsọ osi di daye, ti o nsọ otoṣi di ọlọrọ, ti o si nbọ ili tọbẹ nigbo—Ah eṣe ti ẹyin fi nṣojo be ẹyi ti on gbagbọ kekere oyinbo ni, The more I live, I hope, but why worry, jowọ iwọ ẹni bẹ ti o nka Eko Akete ba mi kọ orin kekere yi:—

Igba wa mbẹ li ọwọ rẹ,
Awa o ṣe bẹru?
Baba ki'o je k'ọmọ rẹ
Sọkun li aimidi.

Oluwa ki nṣe ibi, ẹ sa fi ibi kan wo na, bi ọmọde ba dide to ba ni iṣẹ oninakuna ni on yio gbe dani, o daniloju pe Baba rẹ ki o fẹran rẹ arara. Bẹ gẹgẹ ni ki enia wa ki Ọlọrun fun ni owo tan ki o wa mu na, ni inakuna, bawo ni oṣe le jẹ didun inu Baba wa ni to nbẹ lọrun, owo to ma ṣe ni ni were Oluwa ma fun ni. Inakuna ni ka ma tiro pe, ki Ọlọrun jẹ ki alẹ wa san ju aro wa lọ, mo si rope lai ṣiyemeji ọpọlọpọ enia yio ri si eyi, nje e je ka wa pari ọrọ yi lati tun bere pe kini nje igba tabi tani nlo igba ju—loju awọn enia to nlo igba ju laye, ni ẹniti ko jẹ ẹda kan lowo, to si yẹ ni enia, tosi nluwa ọmọ enia, to si nṣe iṣẹ ọmọ oluwabi—oluwa rẹ gan ni o nlo igba ju. Ṣugbọn mo fẹ ki onikaluku wa mọ pe yala si rere ni o tabi ayipada omiran igba ni lati pasada. Ati pe ipo kipo ti Oluwa ma fi wa si ẹ jẹ ka lo pe'u iwa rere, ati otitọ ki Oluwa ko ṣe atunbọtan wa ni rere, Amin. Ẹ ku Lalai o.

Emi ni tiyin nitoto,

ỌMỌ AWO.

---


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣeṣọ mọ sọ ti awon "Dengẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atupa ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣingo sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣaba Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹyin ara-oke ati ilu miran, ẹ mase gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.


---

CHANGE OF NAME.

S. A. COLEMAN-DANIEL

TO

ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.

Commencing from the 1st day of February, 1928, the public are hereby notified that I, formerly known as S. A. Coleman-Daniel, do now desire to be known and called by the name

ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.

All documents bearing my former name remain valid.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, FEBRUARY 4, 1928.

## ARA EKO, EYI TI JẸ?

Ninu ọsẹ yi ni a gbọ fẹnrẹn pe Ijọba npete ati ṣe ipade kan ninu eyiti nwọn yio pe awọn isọri-isọri sibẹ, a si gbọ pe ohun ti a o mu ṣe nibẹ ni pe bi Ijọba yio ti ṣe le ṣe aṣaro lati to iye-owo ti nwọn yio ma san fun gbogbo awọn oṣiṣẹ ( *Artisans* ), iru aba ati ete bayi ṣe ni loju sũ; nitori lalai si irufẹ ipade ti a gbọ pe Ijọba npete rẹ yi ni olukuluku ile-iṣẹ Ijọba ti nsan owo ti o yẹ fun olukuluku oṣiṣẹ gẹgebi mimọ-iṣe wọn ti ri, ki lo ha tun ko si Ijọba lori lati tun sọ pe pẹpẹsẹ awọn yio ni ipade kan fun ṣiṣe akoso irufẹ owo ti nwọn yio ma san fun awọn oṣiṣẹ wọnyi gẹgẹbi ati gbọ̃ si? Loju wa ọna inira omiran ni a ro pe Ijọba tun mba bọ yi, ṣugbọn a ko le ṣiwaju ẹlẹdẹ pupọ: ni koi pẹ yi ẹwẹ ni a ri eto ti awọn Municipal to nipasẹ ti owo ti ẹnikẹni ti o ba fẹ wọ mọto ni lati ma san fun awọn Awamọto; ọkan ninu eto na sọ bayi pe owo ti ẹniti o ba fẹ wọ mọto lati Ita Tinubu de Ọbun Eko ko ni ju kọbọ kan lọ fun enia kọkan.

Lati Ita Tinubu de Ebute Mẹta ko ni ju kọbọ meji lọ: awa ko mọ idi rẹ ti Ijọba fi njoye Alatojubọ si nkan onikan bayi, ki iṣe ọran-iyan fun ẹnikẹni lati wọ mọto lọ si ibikibi: bi a tilẹ sọ pe awọn awamọto ngbowo pupọ lọwọ ero, a ṣebi nisisiyi ti Mọto Akero pọ bi iyẹpẹ, awọn ero mọ ati wọ eyiti owo wọn rọju ki nwọn si ṣa olowo geregere ti: a si tun gbọ pe awọn Municipal tun bu owo si iwe *Licence* mọto nisisiyi, anisẹ wiwọn ni nwọn nwọn pupọ ninu awọn mọto wọnyi, mọto di wiwọn bi ekurọ, Igida! l'ọtun l'osi, ni o dabi ẹnipe Ijọba ntubọ ndi ẹru wiwuwo le ori ilu, nipasẹ orișiriși owo ti a nbu le awọn ohun elo ilu, eyiyi ko ma ti kan olubori owo ti nwọn npete lati bẹrẹ si gba l'ọdunni, eyini ni owo-asingba ( *Income Tax* ) nipasẹ inira ati airi ọkan ṣe kan ti o mbẹ l'Eko, o dabi ẹnipe Ijọba ki gba eyi gbọ, nitotọ nwọn le ma ri pe nkan se gbẹdẹ fun ilu nipa inawo ti ẹlomiran nṣe fun igbeyawo, tabi isinku, ọwọ baba ni Ijọba nwo, nwọn ko wo ẹsẹ baba: owo-yiya ni ele geregre ko ṣai wa ninu irufẹ inawo bayi, gbogbo ohun ti o ba ndan kọ ni wura: a nke to pe orișiriși owo-asingba wọnyi npa òwò l'oku ni; ni lọlọyi ni Alagba kan sọ nipa ti awọn Egbẹ Onișowo Indian kan ti nwọn mbẹ nilẹ yi ti nwọn ko si jinna si 'le Alagba yi pe o ku ẹkun oju ki awọn Indiian Onișowo wọnyi ki o ma sun puru-puru bi ọmọ titun nipasẹ aita ọja Ṣabu wọn ati papa nipasẹ owo Ibode girimọyan ti a sọ pe o ndi tita pupọ ọja won lọwọ. Ọrọ re o: ẹnikẹni si mọ dajudaju pe bi awọn Indian wọnyi ti nke, bẹni ọgọrọ awọn Onișowo miran nke pẹlu, nkankan dandan lo ṣa ma gbẹhin gbogbo irahun wọnyi, ilu Eko fun ju ẹja panu lọ, sibẹsibẹ Ijọba ko dawọ ofin owo titun ni gbigba duro: a mbẹ wọn ki nwọn maṣai da ọran yi ro.

Korokoro la lu Ifa aditi, ( owe ni o ).

## IRẸPỌ TABI UNITY.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI JANAKU ]

Mo bẹrẹ f'oji

Ninu iwe irohin *Akede Eko* ti *Thursday* Alamisi ọjọ kọkandinlogun oṣu *January* to pari ni ijẹta ni a tẹ wosika ni ede Oyinbo lati ọwọ Alufa J. G. Campbell nipasẹ bi o ti dara to fun gbogbo Ilu lati wa ni irẹpọ. Gẹgẹ bi Oniwasu, iwasu rẹ yi dara pupọ, inu wa yio si dun lọpọlọpọ lati ri wahala, tabi ayan, tabi itara to wa larin awọn Oniwasu papa fun irẹpọ larin ara wọn, ati irẹpọ larin Ilu.

Irẹpọ jẹ ohun ti o dara pupọ, agbajọ ọwọ ni a fi nsọ aiya; alainirẹpọ ati aifẹni gbogbo to wa larin wa ti ṣe ọpọlọpọ jamba si arin ilu; bi ẹnikan ndi i, ẹnikeji yio ma tu u. Ọlọrun Ọba nikanṣoṣo de lo mọ ijọ ti ao mọ dajudaju pe Ifẹ akoja ofin.

Anu ṣe ni pupọ lati ṣe akiyesi pe gẹgẹ bi orilẹ ede, pupọ ninu wa go titi, a fẹrẹ le ma fi ẹnu họ'ra; bikoṣe bẹ, a ha le ri ẹnikẹni to nja fun ire ilu larin wa, ki a si tun ma ri awọn elomiran ti yio ma wa iṣubu ati iparun onigbeja bẹ lojojumọ, bi igbati enia ngbe ja afọju, to tun ngbẹhin ko ni l'ẹsẹ.

'Irẹpọ dara nitotọ, ṣugbọn irẹpọ ni obi, o ni akọ, akọ irẹpọ lo si irẹpọ larin wa nibi. Irẹpọ awọn larin awọn Ọlọtẹ lati ba Ilu jẹ, irẹpọ larin onișekuṣe lati ba alafia ile onile jẹ, irẹpọ larin awọn ọmọ jaguda lati t'ọwọ bọ apo alapo, irẹpọ larin olowo lati jẹ talaka ni iyá, irẹpọ larin awọn baba isinku lati ko ogun ologun jẹ, ati oniruru irẹpọ buruku miran lo pọju, gẹgẹ bi a ti wi ṣiwaju, larin wa.

Ofin buruku miran ti Ijọba ti so mọ wa l'ọrun, irufẹ irẹpọ buruku bayi lo jẹ ki pupọ ninu wọn ṣe so; ofin pupọ ti ko dara ni a ba si ti le sọ di oku, bi ko ba si abinuku, ilara ati alaisi irẹpọ to peye.

Ojukoro, ole, anikanjọpọn, igbraga ndá ọpọlọpọ ẹlomiran lāmu; bi nwọn ba jẹjẹ oye C.M.G. fun ẹlomiran, ko kọ lati ṣe atilẹhin fun Ijọba ki o gba gbogbo ile wa lọwọ wa, ki o si le wa junu si ẹhin odi, bi Ijọba ba buru to lati da iru abá bẹ.

Omugọ nyọ ẹlomiran l'ẹnu, iru awọn ẹni bẹ, Oyinbo ko le jẹbi ọrọkọrọ loju wọn, Enia Dudu ko si le jare lori ọrọkọrọ, eyikeyi ti Oyinbo ba ti ṣe ṣa lo daaa loju wọn. Bawo ni irẹpọ atata ti ṣe le si larin wa nigbana.

Ju gbogbo rẹ lọ, ki ẹni to nṣe ibi ma ṣe nṣo, ẹni ti o nṣe rere bakana, tika tore ki ngbe. Ko si ẹnikẹni l'aiye to le da iṣẹ Oluwa duro, talo njẹ enia, ani enia ti Ọlọrun le parẹ tile tile, tọmọ tọmọ, kuro l'aiye nigbakigba ti ko ba kuro nidi ibajẹ. Pakute Ọlọrun ko s'ẹni ti ko le mu. Ẹ lọ ṣọra. nyin, ki ẹ si ranti iwa.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### On Leave.

Mr. Emanuel Ọla Macaulay, 1st Class Clerk, Nigerian Railway, Traffic Audit, Ebute Mẹta, is on one month's vacation Leave, as from the 13th January, 1928.

Mr. Macaulay proposes to spend part of his leave at Ede, Ọffa and Ile Ife.

### Resumption of Duty.

Mr. Albert O. Beckley, 1st Class Clerk, Nigerian Railway Transportation Department, Ebute Mẹta, who has been spending part of his leave at Abẹokuta with his Brother, George T. Beckley, Esq., President Judge, Native Court, Grade B, Ake, Abeokuta, has resumed his duties, as from Monday, the 30th ultimo.

### Promotions.

Mr. Ige Famosa, 2nd Class Compositor, Railway Press, Ebute Meta, has been promoted to 1st Class Compositor, with effect from the 1st January, 1928.

---

Mr. W. A. Sanyaolu, 3rd Class Compositor, has been promoted to 2nd Class Compositor, as from 1st January, 1928, vice Ige Famosa promoted. Congratulations.

## Death of Lord Haig.

### A GREAT WAR FIGURE.

### COMMANDER OF THE BRITISH EXPEDITIONARY FORCE.

**The death is announced in London, on Monday night, the 30th January, 1928, of Field Marshal Earl Haig. Aged about 67 years—Sympathy to the Lady Haig.**

According to the *Nigerian Daily Times* of the 1st February, 1928, which reads—"The final decision regarding the place and date of Lord Haig's burial has not yet been announced but it is certain that he will be accorded the full honours of a military funeral. Regulations provide that a Field Marshal must be given a salute of 19 guns and that six battalions of troops with eight squadrons of calvary shall attend. The Pall-bearers, it is laid down, shall all be of the same rank as the dead officer.

Lady Haig has expressed the hope that those sending floral tributes will buy Flanders Poppy wreaths made severely by disabled ex-service men in the factories at Richmond and Edinburgh which Lord Haig himself established and in which he took so much pride. It is felt that there can be no more appropriate tribute to the Field Marshal's great work than to help those of his old comrades who although disabled are finding work in Poppy factories."

---

"A Court Circular issued from Sandringham last night contained the following notable tribute to Lord Haig from the King:—

"The King has learnen with profound sorrow of the death of Field Marshal Earl Haig who will for all time be remembered as Commander-in-Chief of His Majesty's victorious armies in the field. The King knows that the sudden and irreparable loss of this valuable life will be deeply felt throughout the whole Empire by the Army and more especially by Lord Haig's old comrades to whose welfare he had devoted himself since the close of the great war."

## Death of Master Ajetunmobi.

It is with deep regret we have to chronicle the death of Mohammed Shittu Ajetunmobi, a school boy, and the son of Mr. Asani Mohammed Ajetunmobi, Storekeeper at Mr. J. H. Doherty's Shop, Alakoro, Lagos, which sad event took place on Saturday morning the 28th January last, at 9 a.m.

Boy Shittu had been indifferent health through the alle ed severe beating of "Alikali Masquerade" during Christmas or New Year season. The deceased boy left his parents, younger Brother and Sister to mourn his untimely death at the age of 16.

To the father Mr. A. M. Ajetunmobi, and his mother Madam Asana, and to the rest family of the deceased, our sincere sympathy. *R.I.P.*

## Death of Mammy Elizabeth Fisher.

The death took place at 37, Richards' Lane, Lagos, on Friday night, the 26th January, 1928, of Mammy Elizabeth Fisher.

Her mortal remains were removed to the African Bethel Church the following day at 4 p.m., and thence to Ikoyi Cemetery for interment. A Musical Band marched before the corpse to Ikoyi Cemetery.

The deceased Mammy left behind a large family including children and Grandchildren to mourn her loss at the age of 80.

To her son Mr S J Fisher, her daughter Mrs. Suru Smith, her son-in-law Mr. J G. Jones her grand children Mrs Caroline Buckror and Mrs Fanny Cole and all the rest of the families, our condolence.

May her soul rest in peace.

### Death of Mr. T. Ogunmefun.

The death is announced at 45, Igboșere Street Lagos, of Mr. Michael Thomas Ogunmęfun, Chief Clerk, C.M.S. Bookshop, on Wednesday afternoon at 1 30 p.m.

His mortal remains were removed to Christ Church Pro-Cathedral the following morning at 9 a.m., and from thence to Ikoyi Cemetery for interment.

To Rev. I. B. Ogunmęfun, his brother, and to his children Mr. Ębun Ogunmęfun, Mr. Olu. Ogunmęfun and all the bereaved families our profound sorrow. *R.I.P.*

### Alas ! My Sister.

It is with profound regret that we have to chronicle the death of Miss Paula Aina Macaulay, daughter of Mr. Herbert Macaulay, C.E., at Kirsten Hall, Balbina Street, Lagos, on Friday, the 27th January, 1928, at about 4 p.m. of the clock.

The deceased had been laid up since seven months ago, but for her illness her marriage to Mr. Albert Johnson of the Niger Company, should have taken place in November, 1927, when it was deferred until she is no more on earth.

Her remains were removed to Holy Cross Cathedral, (Catholic), before a large concourse of people Rev Father Freyburger officiated. And thence to Ikoyi Cemetery for interment.

Miss Paula Aina Macaulay breathed her last at the age of 23 and eighteen days.

To her parents, brothers and sisters, and all the relatives of the deceased family, our heartfelt sympathy.

Alas ! my sister.

---

ORI II.

## IWA—AGBARA TI ĘKO ILE NI.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KĘSAN.

---

Napoleon Buonaparte saba ma sọ pe "bi iwa rere ni, bi buburu ni, ọmọ yio hu lẹhin ọla, ọwọ iya rẹ ni o wa." On papa ka ti ipo nla ti on de laiye si ti pe ẹkọ aya-nini, itara ati ikamba ara ẹni ti iya rẹ kọ o ni kekere ni o jẹ pataki eyi ti o gbe on de ipo yi.

Ọkan ninu awọn opitan rẹ sọ pe, "ko si ẹnikan ti o kawọ rẹ afi iya rẹ, ẹniti o wa ọna lati mu u ni ifẹ, ọwọ ati ki o ma gbọran si on lẹnu, nipa fifi ọwọ-ife, ọwọ lile ati ona ẹtọ nwọn-tun-wọnsi mu u; lati ọwọ rẹ ni o ti kọ iwa iteriba tabi igbọran."

Ninu ọkan ninu awọn iwe-irohin nipa ile ẹkọ ti Mr. Tugwell kọ, a se akiyesi apẹrẹ pataki kan ti o ya bi ra nonu le, nipa bi iwa iya ti lagbara to lori iwa awọn ọmọ. O sọ pe eyiyi jẹ otitọ, ti ko si tabi abi kan ninu rẹ tobẹ ti awọn onișowo ninu ile ișẹ wọn a ma lo o. O ni "ninu ile ișẹ nla kan ni iti ọpọlọpọ awọn ọmọde nșișẹ, nwọn sọ fun mi pe ki awọn ọga wọn to gba ọmọ kan si ișẹ, nwọn a kọkọ wadi iru iwa wo ni iya ọmọ na ni, bi nwọn ba ri i pe iya na ni iwa rere, ọkan wọn a balẹ de aye kan pe awọn ọmọ rẹ yio șe daradara. Nwọn ko fẹ mọ iru iwa ti baba rẹ ni."

A si tun șe akiyesi pe bi baba ba jẹ enia rederede—ti o di ọmuti, ti o di ițanmu—bi iya ba gbọn ti o ba mọ nkan ti o rșe, ile ko ni tu, awọn ọmọ wọn si le de aye kan ni aiye; șugbọn bi o ba șe pe iya ni o di ẹni rederede, bi o ti wu ki baba le mọ iwa hu to, o șoro ki awọn ọmọ wọn to jẹ nkan laiye.

Diẹ ni a nri ti a si mọ nipa ọna ti agbara iwa iya ni lori iwa ọmọ. Nipa ais mi ati aibaye ati nipa ikunrimo pẹlu suru ni nwọn a fi yanri ișẹ wọn ni iyẹwu ile wọn. Nitoriti awọn ișẹ ribiribi ti nwọn șe yanri, jẹ ninu ile wọn ati ni ipamọ, a ki isaba kọ wọn silẹ fun kika awọn eni; ani ninu itan aiye awọn ẹn nla papa. a ki isaba gbọ nipa ti ira ti iya wọn ko nipa ki kọ wọn ni iwa hu ati nipa uidari wọn si ọna ti o tọ. Șugbọn eyi ko ni ki awọn iya wọnyi ma ri ere ișẹ won. Bi a ko tilẹ kọ awọn ișẹ ti nwọn șe lori awọn ọmọ wọn silẹ, sibẹ awọn ișẹ wọnyi a gbẹhin wọn, ere wọn a si ma pele si titi aiye.

A ki isaba gbọ nipa awọn obinrin ti o jẹ ẹni nla, bi a ti ngbọ nipa ti awọn ọkọnrin. Eyiti a ma ngbọ ju ni ti awọn obinrin rere; o si le jẹ pe nipa pe iwa ti nwọn fi kọ ni, ni imọ ni ara, je ișẹ ti o firi ișẹ miran bi ki nwọn ma kẹrẹ ninu ișẹ ọna aworan, ninu ișẹ iwe kiko tabi ninu wiwe ewe orin-ete.

Joseph de Maistre ni, "Otitọ ni awọn obinrin koi ti șe 'Iosi bo ti ri ni' iwe. Nwọn ko kọ iwe 'Iliad' tabi 'Jerusalem

Delivered' tabi 'Hamlet' tabi 'Shaedre' tabi 'Paradise Lost' tabi 'Tartuffe'; nwọn ko we ewe kikọ Church St Peter, nwọn ko we ewe orin 'Messiah,' nwọn ko gbẹ ere 'Apollo Belvidere,' nwọn ko fi ọna-oju ṣe aworan 'Last Judgment'; awọn kọ ni o da Algebra sils tabi iworan ti a fi nwo awọn irawọ loju ọrun, tabi ẹrọ-ọkọ; ṣugbọn nwọn ṣe ohun ti o firi gbogbo wọnyi, nitoripe awọn ni o tọ awọn ọkọnrin ati awọn obinrin ti o jẹ olododo ati oniwa rere—awọn wọnyi si ni ohun ti o dara julọ ni aiye."

Ninu awọn iwe ti De Maistre kọ, o sọrọ iya rẹ pẹlu ifẹ ati ọ̀wọ̀ ti ko kere. Iwa rere iya rẹ mu ki awọn obinrin miran ni'yi loju rẹ. Nigbati o nsọ irufẹ enia ti o jẹ, o pe e ni "iya mi ẹni ọwọ"—"Malẹka ti Ọlọrun gbe awọ enia wọ fun igba diẹ." O ni ọpẹ iya on fun iwa ti on nhu ati fun ọna rere gbogbo ti on ntọ; nigbati o si dagba ti a yan a ni ikọ lọ si Court St. Petersburg, o sọ pe iwa ati ẹkọ ti iya on kọ on ni eyfti on nlo.

Bi o ti jẹ pe enia wuruwuru kan loju ni Samuel Johnson, ọkan ninu ohun ti a gbadun ninu iwa rẹ na ni ti ahọn tutu ati ifẹ ti ifi ma sọro iwa rẹ nigbakugba—obinrin ti oye ori rẹ ko kere, gẹgẹbi Samuel Johnson tikararẹ ti sọ, on ni o kọkọ mu mọ ohun ti a npe ni ẹsin. Nigbati nkan tilẹ di piti fun, ninu iba diẹ ti o ni, ki iṣai lo pupọ fun itọju iya rẹ; ọkan ninu iṣẹ igbẹhin ti ọmọ iṣe fun obi ti o ṣe ni, ṣiṣe iwe ti a npe ni 'Rasselas', ki o ba le ri owo san awọn gbese pẹpẹpẹ ti iya rẹ jẹ ati lati fi sinku rẹ.

Ọmọ ọdun mọkanla pere ni George Washington nigbati baba rẹ ku, ti o da ọmọ marun pẹlu opo iya wọn silẹ. George ni agba. Iwa rere iya wọn ko lẹgbẹ—ọgbọn rẹ pọ, o mọ ọwọ yi pada, o mọ ile tọju, o si kawọ ọkanjuwa rẹ.

Ati kọ awọn ọmọ rẹ ni ẹkọ ati tọ wọn, gbogbo rẹ di ọwọ rẹ. O ni lati ṣe akoso awọn ti o wa labẹ rẹ ninu ile, o si ni lati ṣe alabojuto gbogbo ile ati ilẹ janrẹrẹ ti nwọn ni, gbogbo nkan wọnyi ni o si ṣe ni aṣeyanri perepere. Ero pipe, aigẹlẹtẹ, iwa pẹlẹ, iṣẹ ṣiṣe ati aifi ara silẹ, iwọnyi ni o mu u ṣẹtẹ gbogbo iṣoro tabi idiwọ; o si wa jere gbogbo ayan ati iṣẹ rẹ, iṣe rẹ ṣe oju rẹ, gbogbo awọn ọmọ rẹ ni o de ipo loju ẹmi re, olukuluku wọn ni aye tirẹ ni o ni orukọ rere, eyiti o jẹ iyi fun awọn tikara wọn ati fun awọn iya wọn, amọna kanṣoṣo 'i nwọn ni, ti o fi ẹsẹ wọn le ọna iwa ti nwọn nhu.

*Translated By*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

## Ẹ TETE KIYESI ARA!

Oniwe irohin yọwọ bun mi li aye diẹ ninu iwe rẹ lati fi akiyesi kekere yi han awọn ara adugbo Adam Street ni Okepopo, bi o ti jẹ wipe bi enia ba fi ina si ori orule sun dajudaju oluwarẹ yio ri ohun ti ko tanma arara.

Ẹ ba bi wa lere pe oye kini a ri ti a nfẹ sọrọ le lori, oye mi na ni wipe nigbakugba ti irin ba gbe wa rekọja Adam Street ni Okepopo yi a nṣe akiyesi ni ọpọlọpọ igba yi lati ma gbọ kiki ẹiyẹ kan ni ori igi nla Bẹrẹfutu ( Breadfruit Trees ) ti o dojukọ ile Alfa kan ti o njẹ Sumọnu Arole, ẹiyẹ na ma nke nigbamiran ni iwọn agogo mẹwa alẹ tabi ju bẹ lọ kike ti ẹiyẹ na si nke e, mu mi ṣe ofintoto rẹ larin adugbo na, mo si gbọ wipe ẹiyẹ buruku ni ẹiyẹ na, eyiti mo gbọ wipe ni poroporo igba ti ẹiyẹ na ba nke enia ni lati ṣe alaisi.

Nwọn si sọfun mi wipe bẹni ẹiyẹ na nke nigba kan eyi fẹrẹ to ọdun mẹwa nisisiyi, ti awọn enia si nku gburu ni gbẹgbẹlẹ adugbo yi, njẹ bi ọran na ti jẹ yi, o tọ o yẹ ki a fi si akiyesi ẹnyin ara adugbo yi wipe ina ni ẹ nfi si ori orule sun, bẹ bi enia ba fi ina si ori orule sun ẹnyin na mọ wipe ọwọ ewu ni.

Ẹ ṣe ṣawura lati le ẹiyẹ buruku yi kuro ni adugbo nyin, larin ọsẹ yi oku meji li a gbọ wipe o ku ladugbo yi, ọkan ọmọde ekeji agbalagba, ṣugbọn o jọ gati ko jọ gate ko fi ẹsẹ mejeji tiro, papa gidi irufẹ ẹiyẹ bẹ ko dara lati ma ke larin ilu, nigbati ẹiyẹ kan wa ti o jẹ wipe ki nke lọsan afi ni oru, papa ti ko tilẹ si ẹniti o le sọ wipe on mọ irufẹ ẹiyẹ wo ni ẹiyẹ na nṣe, ẹ ko ri wipe Alijọnnu ẹiyẹ ni iyẹn, bi ẹ ko ba wa ọna ti ẹiyẹ na fi le kuro nibẹ lati iwoyi lọ ẹnyin ara Adugbo papa Alfa ti a darukọ pe ile rẹ dojukọ igi ti ẹiyẹ na nke

lori rẹ, ao ba awọn onilu sọrọ ninu iwe wipe ki awọn ri si gige igi na lulẹ, fun itori irọra ati alafia awọn ara adugbo nyin.

Emi ni,

ALAKIYESI.

## THE IGBAJỌ UNION.

Awọn Ẹgbẹ Ọmọ Igbajọ to wa ni Ebute Mẹtta ati ni Eko nibi ti a darukọ wọn si Oke yi ṣe ohun lọdun ni, ni akoko ọdun.

Ohun ikini ti akọkọ ri ni wipe won jẹ oye bi mẹjọ titun larin wọn, awọn oye na ni iwọnyi:—

1. Bandele Jayeọla—Baba Ẹgbẹ.
2. Phibe Ajayi—Iya Ẹgbẹ
3. Elisabeth Ẹgbẹninhun—Iyalode.
4. Mary Tọmọri—Iyalaje.
5. Phibe Oyewẹ—Ajigbeda.
6. Mariani Bọlaji—Ọtun Iyalode.
7. Jannet Dada—Ọtun Iyalaje, ati
8. Dorcas Jokotade—Ọtun Ajigbeda

Ki ha lohun ara tari ? Ao ti ri awọn Ẹgbẹ ti o fi ara wọn joye ri ni tabi kini iwun ara? Bẹni, gbogbo iwọnyi lati ri ri, On ta ṣe pe ni ohun ara ni wipe ẹni kọkan ninu awọn Oloye wọnyi lo wu ye rẹ to ṣepe inawo fun awon Ọmọ Ẹgbẹ yi ni ọtọtọ, ti Ilu, ati ijọ nlọ larin wọn ni akoko ti olukuluku wọn, ohun ti a fi pe ni ohun ara niyi. Ati wipe ni ọjọ Ọdun gangan (Christmas Day) ni Baba Ẹgbẹ Wuye ti ẹ ki nwọn to bẹrẹ si jẹ ki wọn to bẹrẹ si mu, ki nwọn to bẹrẹ si jo. Igba ti gbogbo wọn ti pe gba patapata, ni ọdọmọkunrin kan ninu wọn ba fo sarin wọn to bẹrẹsi ran wọn leti ọdun tokọja (1926) bi awọn ti ṣe ofo Ẹmi to ninu Ẹgbẹ wọn, o bẹrẹ si sọ bayi:—

Mary Ominihun, Iyale ile ni Oku.

Bọlaji Iyale ile ni o bi ọmọ tan ati on ati ọmọ to bi loku.

Akanni Ipeaiyeda, Ibidun Faṣọyin, ọmọ wa ni awọn mejeji yi, ara awọn ti an nmu omi le lori loni di ọla pe awọn wọn yi ni yio mu Igbagbọ dun lẹhin ọla, gbogbo awọn yi ta darukọ lo ti ku, a ko si le ri wọn mọ lailai.

Ye, Ila ta mu diyan ọbẹ ẹran wọle ẹran mula jẹ. Ọṣungbẹgẹ ta mu diyan ọbẹ, Ẹran wọle ẹran mujẹ.

Ọtọtọ abiyamọ meji ti ara Igbajọ di yan le lori pe nwọn o bi ọkunrin nwọn o bi obinrin iku wọle iku mu wọn lọ. Iku pa Bọlaji, lai jẹ ko bi mọ s'aiye, Iku pa Ominihun o fi ẹyọ ọmọ kan ṣoṣo kekere s'aiye, a! Ẹnyin Ẹgbẹ Ominihun ẹṣe Ọmọnihun lore, ọmọ orukan ni, ẹṣe lore nitori wipe ẹni to ṣẹhin doku ara rẹ lo ṣẹhinde.

Ye, Ye, Igbajọ Union, koko si lọ lẹgbẹ Igi Afomọ si lọ lọrun Ọpẹ Oyin ṣilọ ninu afara, Bọlaji, Ominihun, ẹnyin mejeji lọ nilẹyi ẹtun wa ma awo ṣi awo lọ.

Oyin ta fẹ la ba tirẹ yin tan, ta fun yin loyin gbẹ, ẹ'wo Ọwọrọ Ojo tafẹ fi wẹ ba ti bọsi, bẹ loda, A! A! ẹwa wo Akanni tani yio kọ iwe lati mu Igbajọ lọ si waju, bi o ti di ọmọ ọdun mẹjọ lo ku. Ibidunnlọla, ta ni yio kọ ṣẹ ọna ọlọwọ lati mu Igbajọ lo siwaju lọla, bo ti mọ rọ sọ tan lo dakẹ, a o'ma ṣeo mo ṣe ba wo ni ṣoro lẹhin awo Amọbọlọjọ aṣorodẹkun, ọmọ ẹni ni ṣoro lẹhin ẹni Ye, iku doro, Baba Akanni lo ṣoro lẹhin Akanni, Baba Ibidunlọla lo ṣoro lẹhin Ibidunlọla.

Ye, o ma ṣe o, wọn ti lọ, gbogbo wọn lo ti lọ. Odi gbere, o darin na ko o doju ala firi o doko Alawo, ka to tun leri gbogbo won, o di ọjọ ikẹhin, niwaju ẸNI NA ti gbogbo oku yio fi ara han laye, odi ọjọ ajinde ka to tun le ri ra wa.

Ọlọrun jare o, Ọlọrun jare o' ma tun jẹ ka ri iku Aya ati iku Ọkọ laipe ọjọ ma. Ki Olodumare Kjare, ti wa lẹbi ti ẹ lare ko mọ tunjẹ ki a ri atẹhin ku mọ. Lẹhin eyi ni nwọn pe Ọdọmọkunrin kan to gba dura fun wọn. Lẹhin na ni Samuel A. Fabunmi alaga Ẹgbẹ wa fi aṣẹ si wipe ki nwọn ma jẹ ki nwọn ma mu. Ni igbana la wa sunmọ Ọdọmọkunrin kan ta mọ larin wọn, a bi lere wipe ki ni Ẹgbẹ yi fun, o da wa lohun bayi wipe fun iranlọwọ ati ilọsiwaju ilu wa Igbajọ, ni, mo tun bi lere wipe ni pa kini, o wipe nipa owo, mo wipe ẹma da wo, o wipe bẹni, lagbara Ọlọrun aotiẹ maṣe owo pẹlu Ere eyi ti yio jẹ fun ilọsiwaju Ilu wa. Alaga Samuel Fabunmi, mo ba ọ yọ, ọwọ nyin a ran o, gbogbo ẹnyin ọmọ Ẹgbẹ mo ba nyin yọ wọ nyin a ran o. Ki Ọlọrun na to ka pa ohun gbogbo ko ma ṣai ba nyin kapa Gabagebe, Iranṣẹ Iṣu.

Lati ọwọ riro nitenia Ọlọrun Loluṣe.

---

## ARERE O!

Ni ọsẹ to mbọ, a o sọ Itan Igbesi-aiye Ọgbẹni Dada Adeṣigbin Oninure (Ologbe) pẹlu aworan rẹ.

## Disinfectant Soap of Unrivalled Quality

Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.

# MAGNET

## Carbolic Soap Tablets




WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ę ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣę ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as :—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe, awọn ti o nfi iwe ṣiṣę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣę Ewurę pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

# HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same,* if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undertaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

———:o:———

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmin ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn

Pọ ọ si ni owo wọn.


Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 2d, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer